# AWỌN AJAKALẸ ARUN NAA TUBỌ N BURU SI I

## Ẹksodu 8:20-32; 9:1-12

## ẸKỌ 54 ---- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ṣugbọn ẹ mã gbà ara nyin niyanju li ojõojumọ́, niwọn igbati a ba n pè e ni Oni, ki a má bà sé ọkan ẹnikẹni ninu nyin le nipa ẹ̀tàn ẹ̀ṣẹ̀" (Heberu 3:13).**

**I Idajọ Kẹrin: Ajakalẹ Arun Eṣinṣin**

1. A kilọ fun Farao nipa ajakalẹ arun eṣinṣin, Ẹksodu 8:20, 21
2. Mose sọ fun Farao pe a o yọ awọn ọmọ Israẹli kuro ninu ajakalẹ arun naa, Ẹksodu 8:22, 23; Orin Dafidi 34:7; 91:9, 10; II Kronika 16:9
3. A rán ajakalẹ arun naa, Farao si gbiyanju lati ba Mose ati Aarọni rẹ, Ẹksodu 8:24-29; 3:18; Gẹnẹsisi 46:34
4 Oluwa dahun ẹbẹ Mose, ṣugbọn Farao yẹ ileri rẹ, o si tún sé aya le, Ẹksodu 8:30-32; Owe 11:3

**II Idajọ Karun: Ajakalẹ Arun Buburu Lara Awọn Ẹran Ọsin**

1. A kilọ fun Farao nipa ti ajakalẹ arun ti yoo kọlu awọn ẹran ọsin, Ẹksodu 9:1-3
2. A tun yọ Israẹli kuro ninu ajakalẹ yi, Ẹksodu 9:4
3. Lati tun fi han siwaju si i pe iṣẹ-iyanu ni eyi, a dá akoko ti ajakalẹ arun naa yoo bẹrẹ, Ẹksodu 9:5
4. A ran ajakalẹ arun yi, Ẹksodu 9:6
5. Farao wadi bi otitọ ni a da awọn ẹran ọsin ti Israẹli si, sibẹ o sé aya le, Ẹksodu 9:7

**III Idajọ Kẹfa: Ajakalẹ Arun Oowo**

1. A rán ajakalẹ arun oowo lai si ikilọ, Ẹksodu 9:8-10; Deuteronomi 28:27, 35
2. O kọlu awọn alalupayida ati gbogbo awọn ara Egipti, Ẹksodu 9:11
3. Oluwa mu ki aya Farao sé le siwaju si i, Ẹksodu 9:12; Owe 29:1; Ifihan 16:2, 11

## ALAYE

### Ohun ti O Fa Awọn Ajakalẹ Arun Wọnyi

A ti ri i ninu ẹkọ ti a ṣe kọja, idajọ mẹta akọkọ ti Ọlọrun ran sori Egipti, pe a ran ajakalẹ arun kọọkan sori isin ibọriṣa awọn ara Egipti. A ṣe eyi lati fi han pe, ko si Ọlọrun miran bi ko ṣe Jehofa, Ọlọrun Israẹli; ati lati fi han awọn ara Egipti pe, wọn n sin oriṣa ti kò tilẹ ni agbara kankan lori ilu ti a gbé n bọ́ wọn.

Ọpa Aarọni ti a sọ di ejo, ti o si gbe awọn ejo ti ara Egipti mì jẹ iṣẹ-iyanu lati doju kọ bibọ ejo ni Egipti ati lati tako iṣẹ buburu ti awọn alalupayida n ṣe. Ejo jẹ oriṣa kan fun wọn, ṣugbọn kò le gba ara rẹ lọwọ agbara Ọlọrun Israẹli. Bẹẹ gẹgẹ ni, lati bu ẹ̀tẹ́ lu odo Nile ti wọn n bọ ni a ṣe sọ omi rẹ di ẹjẹ. Ajakalẹ arun ọpọlọ ati iná ni a rán lati sọ isin ibọriṣa wọn di yẹpẹrẹ. A o ri i ninu ẹkọ yi pe arun eṣinṣin arun buburu lara awọn ẹranko ati oowo ti a rán si eniyan ati ẹranko wá lati doju kọ iwa ibọriṣa wọn.

A kò ka wi pe Mose gbiyanju lati ja irọ́ awọn alalupayida naa. Oun mọ Ọlọrun rẹ, o si gbẹkẹle titobi agbara Ọlọrun ti a fi hàn an ninu igbẹ ti n jo ati iṣẹ iyanu miran niwaju awọn agbagba Israẹli, eyi ti o de góngo nigba ti ọpa Aarọni gbé ọpa awọn alalupayida mi. Ọlọrun ti ipasẹ Mose dahun nipa ṣiṣe iṣẹ iyanu ti o ga ju ti arun ti awọn alalupayida fi agbara Satani ṣe lọ, nipa ṣiṣe iṣẹ-iyanu ti o ga ju bẹẹ lọ, titi di igba ti wọn kò le ṣe afarawe mọ́. Lẹhin naa, ijẹwọ awọn tikara wọn ko jẹ ki Mose ṣẹṣẹ maa tú aṣiri wọn. Ki i ṣe ti wa lati maa gbeja Ihinrere. Bi a ba waasu rẹ tọkantọkan oun yoo jà fun ara rẹ.

Ohun ti a ni lati tẹnu mọ ni pe Ọlọrun wà, agbara Rẹ ni o bori ohun gbogbo. O yẹ ni tootọ ki awọn ọmọ Israẹli di ominira, nitori isinru ti wọn ti ṣe fun ọdun pupọ. Ṣugbọn ki i ṣe nitori eyi ni o ṣe tọ́ lati dá wọn silẹ. Ọlọrun wọn ni o kọ́kọ́ ni ẹtọ́ si ẹbọ ati isin wọn, o si yẹ ki Farao naa gbọran si I pẹlu.

Nigba pupọ, ọwọ Ọlọrun maa n wuwo si wa lara nigba ti a wà ninu ẹ̀ṣẹ, Oun a si maa ba wa wi nitori iwa buburu wa. O rọrun lati kọ ẹ̀ṣẹ kan pato silẹ -- paapaa ju lọ eyi ti o n ba wa ninu jẹ -- ki a si rò wi pe eyi yoo tu Ọlọrun loju, yoo si pa ẹri ọkan wa lẹnu mọ́. Ṣugbọn Ọlọrun kò beere pe ki a kọ awọn ẹ̀ṣẹ kan silẹ fun iwọn igba diẹ bi ko ṣe pe ki a kọ gbogbo ẹ̀ṣẹ wa silẹ ki a si yọọda ara wa patapata fun ifẹ Rẹ̀. Dajudaju inu Farao i ba dun lati bá awọn ọmọ Israẹli sọ asọye nipa lilọ wọn, gẹgẹ bi ọrọ laarin ẹni meji, ṣugbọn a le ri i pe ohun ti wọn n fẹ tobi pupọ ju eyi lọ. Farao kò fẹ fi gbogbo ọkan rẹ bu ọla fun Ọlọrun Israẹli, ṣugbọn o fẹ wà nipo ibọriṣa rẹ sibẹ. Ẹkọ nla ni a ri kọ ninu eyi. Nigba ti Ọlọrun ba rán ọrọ Rẹ̀ si wa, ko ṣe anfaani lati maa lọ́ ọrọ naa tabi ki a maa yi Ọlọrun po lọna ẹtan. Bi a ba fẹ ri ohunkohun gbà lọwọ Ọlọrun a ni lati lọ si ọgangan ifẹ Rẹ̀ ki a si fi gbogbo rẹ silẹ fun Un patapata.

## Ọ̀wọ́ Eṣinṣin

A ti kilọ to fun Farao ki a to rán eṣinṣin wá. A sọ fun un pe bi ko ba gbọran si aṣẹ Ọlọrun Israẹli ọ̀wọ́ eṣinṣin yoo wá sori wọn. Lai si aniani, iru ajakalẹ arun ọ̀wọ́ eṣinṣin yi pẹlu ọ̀wọ́ eeri wọn ti o le ko arun ba eniyan jẹ ohun ti o buru lati de ba orilẹ-ede. Ṣugbọn Farao kò naani ikilọ naa -- nikẹhin eṣinṣin wọnyi de.

Ọlọrun ko le ṣai ranti awọn ti Rẹ̀. Ni ọdun pupọ lẹhin eyi, boya nigba ti Onipsalmu n rò nipa akoko wahala ti o ṣẹlẹ ni Egipti yi, o wi pe: "Bẽni arùnkárun ki yio sunmọ ile rẹ." Ọlọrun ki i gbagbe awọn ti ọkan wọn pé si I, ti igbẹkẹle wọn si n bẹ ninu Olodumare. Awọn ọmọ Israẹli ni Egipti si jẹ irú ẹni bẹẹ.

Wo iru iyọ́nú ati ifẹ nla ti a fi han ninu Ọrọ Ọlọrun wọnyi: "Emi o si pàla si agbedemeji **awọn enia mi** ati awọn enia rẹ." Awọn eniyan wọnyi n sin awọn oriṣa Egipti, ti wọn si n tẹle ilana isin wọn lojoojumọ, kò ni ìkìya bayi lati ọdọ awọn oriṣa wọnyi ti wọn n sìn. Wọn ni itara ti o rekọja ti ẹnikẹni. Awọn ti a n pè ni oriṣa ilẹ Egipti kò le ṣe ire kankan fun awọn ti o n bọ wọn. Ọlọrun kan ṣoṣo ni o n bẹ! Awọn ọlọrun miran jẹ ohun ti Eṣu da silẹ funra rẹ, lati fi tan awọn eniyan jẹ, ati ki wọn si le gbé nkan miran kalẹ lati fi di afo ti o yẹ ki Ọlọrun tikara Rẹ̀ di.

Iṣẹ ibi nla ti arun buburu yi ṣe mu ki Farao bẹ̀bẹ̀ wi pe: "Ẹ mã lọ ṣẹbọ si Ọlọrun nyin ni ilẹ yi." Ṣugbọn eyi ko tó. Ọlọrun ki i ba eniyan dúna-dúrá tabi ki O gbọjẹgẹ fun ẹnikẹni. Igbọran pipe ni O n beere; kò si ohun miran ti a le fi dipo Rẹ̀. Bi kò ba ṣe e ṣe fun awọn ọmọ Israẹli lati rubọ ni Egipti ni ibẹrẹ, ko ni ṣe e ṣe sibẹsibẹ. Awọn ara Egipti ti i ṣe olootọ si oriṣa ẹranko wọn, ko ni gba pe ki a pa awọn oriṣa wọn rubọ fun Ẹlomiran ti wọn ko mọ̀. Mose pinnu lati tẹle Ọlọrun patapata, o si n fẹ ohun ti wọn beere fun ni akọkọ. Lẹẹkan si i, ọba yi tun fẹ ṣe dunadura, o wi pe: "Ki ẹnyin ki o máṣe lọ jina jù." Mose gbà aṣẹ Farao pe ki Israẹli jade lọ, o si gbadura si Oluwa; nigba ti akoko si tó, eṣinṣin kan kò si kù ni ilẹ Egipti mọ́ -- eyi paapaa jẹ iṣẹ-iyanu nla kan lọtọ.

## Ajakalẹ Arun Lara Malu ati Ẹran-ọsin

Lẹhin ti a ti mu ajakalẹ arun yi kuro, Farao yi ero rẹ pada; Mose si fara han ni aafin lati bẹ̀bẹ̀ fun Israẹli ati lati kilọ fun Farao nipa ajakalẹ arun karun ti yoo wá sori awọn ara Egipti, ṣugbọn ti kò ni de ọdọ awọn ọmọ Israẹli. Ajakalẹ arun naa de nitori pe Farao kọ aṣẹ Ọlọrun, nigba ti arun yi si ti kọlu gbogbo ilẹ Egipti, Farao ranṣẹ lọ wò bi ohun kan ba ṣẹlẹ si awọn ẹran-ọsin ti Israẹli. Ohun ti o ri, yẹ ki o mu un mọ̀ pe Ọlọrun Israẹli ni O n ba Egipti jà, nitori pe ọkan ṣoṣo kò kú ninu ẹran-ọsin Israẹli.

A sọ fun ni pe wọn n sin eṣinṣin ati awọn kokoro miran gẹgẹ bi oriṣa, ọ̀wọ́ eṣinṣin pupọ ti o ba ilẹ naa jẹ yẹ ki o mu awọn ara Egipti korira oriṣa eṣinṣin wọn. Ajakalẹ arun pa ọpọlọpọ ẹran ọsin Egipti, eyi ti wọn n bọ. Gbogbo ọlọrun wọn ni Ọlọrun Israẹli doju ija kọ ti O si dotu tì.

## Oowo Lara Eniyan ati Ẹranko

Ajakalẹ-arun kẹfa, eyi ti i ṣe oowo lara eniyan ati ẹranko tun jẹ kikọlu ọpọlọpọ oriṣa Egipti si i. O de ba wọn lai gbọ tẹlẹ. Iwe itàn sọ fun wa pe, o jẹ àṣà laarin pupọ awọn eniyan wọnyi lati maa fi eniyan rubọ si oriṣa wọn, ati lati sun oriṣiriṣi nkan ki wọn ba a le tu awọn oriṣa wọnyi loju. Lẹhin irubọ yi, wọn yoo da eeru ẹkun ọwọ́ soke, soju ọrun lati kù sori awọn ti o pesẹ sibẹ. Wọn ṣe eyi lati le ibi jinna. Ṣugbọn nisinsinyi Ọlọrun yi gbogbo ami yi pada. Ọlọrun paṣẹ fun Mose ki o bu eeru ninu ileru – lati sọ aṣa wọn di asan – ki o si ku u si oju-ọrun. Nigba ti eeru naa sọkalẹ, ajakalẹ arun nla bẹ́ silẹ lori eniyan ati ẹranko. O ran awọn alalupayida wọnni pẹlu, wọn kò si le duro niwaju Mose nitori oowo naa.

Paulu Apọsteli darukọ meji ninu wọn, Janesi ati Jamberi, awọn ti o wa ninu awọn alalupayida wọnyi, o wi pe ẹni ìtanù ni wọn jẹ ni ti ọran igbagbọ́, ati pe wọn ko le lọ siwaju ju bẹẹ lọ lakoko ti wọn, nitori pe wère wọn fara hàn fun gbogbo eniyan (II Timoteu 3:8, 9). A kò tun gburo awọn alalupayida wọnyi mọ̀ lẹhin ajakalẹ oowo yi. Wọn ti ri ọwọ Ọlọrun ti o ṣe iṣẹ-iyanu eyi ti wọn kò le ṣe afarawe rẹ pẹlu agbara ti wọn. Wọn ti ri ọwọ́ Ọlọrun yi kan naa ti O mu ajakalẹ arun wọnyi kuro lakoko ti O wi – eyi ti o jẹ iṣẹ ami ti o tobi ju rirán awọn ajakalẹ arun naa wá. Ṣugbọn o dabi ẹni pe wọn jẹ ẹni iṣati sibẹ nipa ọ̀ran igbagbọ́, nikẹhin ibinu Ọlọrun jẹ wọn run.

## Ipọnju Nla

Ajakalẹ arun wọnyi ti o ṣẹlẹ ni Egipti fara jọ akoko idajọ ti o n bọ̀ lori aye. A sọ fun wa, ninu Iwe Ifihan, nipa ọpọlọpọ ajakalẹ arun ti a o tu jade sori aye lakoko ti a o da ibinu Ọlọrun sori aye ti o kọ̀ Kristi. Bakan naa ni o ri pẹlu idajọ ti Ọlọrun ran si Egipti, o si tọ́ ki a yẹ ọkan wa wò, ki a baa le kà wa yẹ lati bọ́ lọwọ gbogbo nkan wọnyi ti n bọ wa ṣẹ.

A ri i pe idajọ wọnyi de sori Egipti nitori pe wọn yọnda aye wọn patapata lati sin ohunkohun ayafi Ọlọrun. Ajakalẹ arun wọnyi wá lati ṣi nidi ati lati bi awọn oriṣa keferi wọnyi wò ki a si fi Ọlọrun otitọ́ si àye Rẹ̀. Wọn wá bi idajọ sori awọn ti o kọ Ọlọrun ati awọn ti o fi ara wọn fun isin eke gbogbo.

Lẹhin ti Oluwa ba de, ni igba Ipalarada, ibinu kikoro ati ipọnju Nla yoo wá sori aye yi. Lakoko ipọnju yi, Ọlọrun yoo rán ibinu ati idajọ Rẹ̀. Yoo wá sori Aṣodi-si-Kristi ati gbogbo ọmọ-ẹhin rẹ, awọn ti o ti ta ara wọn fun ọkunrin ẹ̀ṣẹ nì, ti wọn si ti gba ami rẹ si ọwọ́ tabi si iwaju ori wọn. Awọn ajakalẹ-arun Egipti, bi o ti lẹ́rù tó o nì, ki yoo tó nkankan lẹgbẹ awọn ajakalẹ-arun ti a o tú da sori aye nigba ti ibinu Ọlọrun ba sọkalẹ lakoko naa. Ikilọ ni awọn

ajakalẹ-arun Egipti wọnyi jẹ fun wa.  Bi a ba fiye si wọn, wọn yoo ran wa lọwọ lati bọ́ lọwọ ibinu gbigbona Ọlọrun, a o si ni idani-loju pe a jẹ apa kan ẹya ara ologo nì, Iyawo Kristi.

**AWỌN IBEERE**

1. Kin ni ikilọ ti a fun Farao ṣiwaju ajakalẹ-arun eṣinṣin?
2. Kin ni iyatọ ti a fi fun awọn ọmọ Israẹli lakoko yi?
3. Kin ni ajakalẹ-arun yi ṣe fun Farao?
4. N jẹ Farao mu ọ̀rọ rẹ ṣẹ?
5. Kin ni ajakalẹ-arun karun, kin ni o si pa lara?
6. Eeṣe ti Farao fi ranṣẹ si ilẹ Goṣeni ni akoko yi?
7. Ọna wo ni ajakalẹ-arun kẹfa fi kan awọn alalupayida lara?
8. Eeṣe ti Oluwa fi jẹ ki aya Farao se le?
9. Apẹẹrẹ kin ni awọn ajakalẹ-arun Egipti jẹ?
10. Awọn tani yoo bọ́ lọwọ ibinu Ọlọrun lakoko ikẹhin?